# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KẸFÀ, ỌDÚN 2021**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸFÀ 2021 – GBÍGBÓGUN TI ÌWÀ ÌKÀ NÍNÚ ÀWỌN Ọ̀RUN

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin ìyìn àti ìjọ́sìn
7:20 am – 7:30 am Ijẹri
7:30 am – 7:40 am Gbólóhùn Woli / Àdúrà Àdágbà
7:40 am – 7:45 am Orin Ìbẹ̀rẹ̀
7:45 am -7:50 am Àdó ọ̀rọ̀ náà
7:50 am – 8:50 am Ìwáásù àti Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:50 am – 9:00 am Orin àwọn akọrin, Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

### MO LO ỌDUN PUPỌ NINU ẸṢẸ

1. Mo lo ọdun pupọ nin'ẹṣẹ,
Lai bikita fun Oluwa mi,
Lai mọ pe 'tori mi lose ku,
Ni Kalfari.

Egbe
Anu at'ore ọfẹ Rẹ pọ,
O dariji mi lọfẹ nibẹ,
Nibẹ lẹru ọkan mi fo lọ,
Ni kalfari.

2. Ọrọ Rẹ fi ẹṣẹ mi han mi,
Mo wariri niwaju ofin,
Mo jẹbi, ṣugbọn mo n'ireti,
Ni kalfari.

Egbe
Anu at'ore ọfẹ Rẹ pọ,
O dariji mi lọfẹ nibẹ,
Nibẹ lẹru ọkan mi fo lọ,

Ni kalfari.

3. Mo tifi gbogbo rẹ fun Jesu,
Mo ti gba l'Oluwa at'Ọba mi,
Ọkan mi nyọ, mo si nkọ orin,
Ti Kalfari.

Egbe
Anu at'ore ọfẹ Rẹ pọ,
O dariji mi lọfẹ nibẹ,
Nibẹ lẹru ọkan mi fo lọ,
Ni kalfari.

4. A! Ifẹ iyanu to gba ni,
Or'ọfẹ t'o wa mi lawari,
Ogiri ikele ni ti wo,
Ni Kalfari.

Egbe
Anu at'ore ọfẹ Rẹ pọ,
O dariji mi lọfẹ nibẹ,
Nibẹ lẹru ọkan mi fo lọ,
Ni kalfari.

## <u>ỌRỌ̀ AGBÁRA</u>

1. Bàbá, nípa títóbi agbára Rẹ, jẹ́ kí agbára òkùnkùn tó n gbaradì láti tún jẹ́ kí àwọn ogun ayé mi bẹ̀rẹ̀ padà, kú lójijì lónìí, ní orúkọ Jésù.

2. Báyìí ni Olúwa wí: "Máse jẹ́ kí ìjòyè, agbára, aláṣẹ òkùnkùn, ẹ̀mí búburú nínú ọ̀run àti ìwà ìkà ìbílẹ̀ yọ mí lẹ́nu mọ, nítorì èmi nru àpá Ọ̀dọ́ Àgùntàn Ọlọ́run kiri lí ara mi,"
3. Agbárákágbara ibi tó n léfò tàbí so rọ̀ sínú ọ̀run lòdì símí, agbára Ọlọ́run yóò fà ọ́ lulẹ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ìwọ agbára tó nká èsó àyànmọ́ mi lójú àlá, nípa títóbi agbára Ọlọ́run Olódùmarè, ìwọ yóò gba ìparun pátápátá lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn ọjọ́ ogun mi, àwọn ọjọ́ ìbànújẹ́ mi, àwọn ọjọ́ ìpọ́njú mi, ẹ gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, ó tó gẹ́, àkókò yín ti dópin, kú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tó fẹ́ jẹ́ kí àwọn àlùmọ́nì mi kú mọ́mi nínú, agbára Ọlọ́run yóò fi ọ́ ṣòfò lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn ẹ̀mí òkùnkùn tó n poùngbẹ fún ẹ̀jẹ̀, tí wọ́n yàn kó jẹran ara mi, kósì tún mu ẹ̀jẹ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.

**<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍÍDÌ 91</u>**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo irinṣẹ́ òkùnkùn tí wọ́n nló láti fimí sínú ihò ìdádúró, gba iná, ní orúkọ Jésù.
4. Ìwọ orùn, osùpá àti àwọn iràwọ̀, ẹ dìde, kí ẹ sì bẹ̀rẹ̀ siní mú ojúrére bámi, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ètò búburú, tí àwọn osó àti àjẹ se lòdì sí ayé mi, túká, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Ohunkóhun íbi tí wọ́n yóò sètò sínú orùn, osùpá àti àwọn iràwọ̀ lòdì sí ayé mi lónìí, túká, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ohun tó lòdì, tí wọ́n kọ sínú obìrí osùpá lòdì sími lónìí, parẹ́, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**II Krónīkà 7:14** Bí àwọn enìyàn mi tí à npè orúkọ mi mọ́, bá rẹ ara wọn sílẹ̀, tí wọ́n bá sì yípadà kúrò nínú ọ̀nà búburú wọn; nígbàná ni èmi Ó gbọ̀ láti ọ̀run wá, èmi Ó sì dàrì ẹ̀ṣẹ̀ wọn jì, èmi Ó sì wo ilẹ̀ wọn sàn.

**II Kọ́ríntì 5:17** Nítorínà bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Krístì, ó di ẹ̀dá tuntun, ohun àtijọ́ tí kọjá lọ; kíyèsì i, wọ́n sì di tuntun.

**Éfésù 6:13** Nítorínà ẹ gbé gbogbo ìhámọ́ra Ọlọ́run wọ̀, kí ẹ̀yin kí ó lè dúró tiri sí ọjọ́ ibi, nígbàtí ẹ̀yin bá sí tì ṣe ohun gbogbo tán, kí ẹ sì dúró.

**Ìfihàn 3:21** Ẹnití ó bá ṣẹ́gun lí èmi o fifún láti jókò pẹ̀lú mi lórí ìtẹ́ mi, bí èmi pẹ̀lú tí ṣẹ́gun, tí mo sì jókò pẹ̀lú Bàbá mi lórí ìtẹ́ rẹ.

**Orin Dáfídì 37:4** Ṣe inú-dídùn sí Olúwa pẹ̀lú, Òun Ó sì fi ìfẹ inú rẹ fún ọ.

**Rómù 12:21** Máṣe jẹ́ kí búburú ṣẹ́gun rẹ, ṣùgbọ́n fi rere ṣẹ́gun búburú.

**I Jòhánnù 2:13** Èmi nkọ̀wé sí nyín, ẹ̀yin bàbá, nítórití ẹ̀yin ti mọ ẹnití ó wà lí àtètèkọ́ṣe. Èmi nkọ̀wé sí nyín, ẹ̀yín ọ̀dọ̀mọ́kúnrin, nítórití ẹ̀yin ti ṣẹ́gun ẹni búburú nìì. Èmi nkọ̀wé sí nyín, ẹ̀yin ọmọ mi, nítorí ẹ̀yin ti mọ Bàbá.

**I Jòhánnù 2:14** Èmi kọ̀wé sí nyín, ẹ̀nyin bàbá, nítórití ẹ̀yin ti mọ̀ ẹnití ó wà lí àtètèkọ́ṣe. Èmi tì kọ̀wé sí nyín, ẹ̀nyin ọ̀dọ̀mọ́kúnrin, nítórití ẹ̀yin lí agbára, tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sì dúró nínú nyín, tí ẹ sì ṣẹ́gun ẹni búburú nìì.

**Orin Dáfídì 126:5** Àwọn tí nfí omijẹ́ fún irúgbìn yóò fi ayọ̀ ka.

**Orin Dáfídì 119:111** Ẹ̀rí rẹ ni ogún mi láíláí: nítorí àwọn lí ayọ̀ inú mi.

**Owé 17:22** Inú-dídùn mú ìmùláradá rere wá: ṣùgbọ́n ibinujẹ ọkàn mú egungun gbẹ.

**III Jòhánnù 1:4** Èmi kò ní ayọ̀ tí ó pọ̀jù èyí lọ, kí èmi kí ó ma gbọ́ pé, àwọn ọmọ mi nrìn nínú òtítọ́.

**II Kọ́ríntì 6:10** Bí ẹnití ó kún fún ìbìnújẹ́, ṣùgbọ́n àwa nyọ̀ nígbàgbogbo; bí tálákà, ṣùgbọ́n àwa nsọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ di ọlọ́rọ̀; bí ẹnití kò ní nkan, ṣùgbọ́n àwa ní ohun gbogbo.

**Oniwasu 9:7** Ma bá tìrẹ lọ, ma fi ayọ̀ jẹ oúnjẹ rẹ, kí o sì ma fi inú-dídùn mu ọtí-wáínì rẹ: nítóripé Ọlọ́run tẹ́wọ́gbà ìṣẹ́ rẹ nísísiyì.